# IBI MIMỌ́ JULỌ: APẸẸRẸ IFIWỌNI AGBARA ẸMI MIMỌ́

## Ẹksodu 26:31-35; 37:1-9; 40:20, 21, 34-38;Lefitiku 16:2; Iṣe Awọn Apọsteli 2:1-4; Heberu 9:6-8; 10:19-22

## ẸKỌ 74 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Emi ó si bère lọwọ Baba, on ó si fun nyin li Olutunu miran, ki o le mã ba nyin gbé titi lailai" (Johannu 14:16).**

### La Ibi Mimọ Kọja

A kò i ti sọ nipa iyara inu Agọ ti a n pè ni Ibi Mimọ́ Julọ. Iyara yii jẹ́ ẹsẹ̀ mẹẹdogun ni gigun ati ni ibu o si jẹ ẹsẹ̀ mẹẹdogun ni giga, a si fi aṣọ ikele, aṣọ ọgbọ ti o wuwo, alawọ ofefe, pupa, elese aluko, ati wura, gé e. A fẹ lati fiye si i gidigidi pe ko si ọna sinu iyara yii ayafi lati Ibi Mimọ́. Ko si ẹni ti o le wọ ọ afi olori alufaa, oun paapaa lẹẹkan ṣoṣo lọdun si ni, ni Ọjọ Etutu. A mọ̀ pe o ni lati jẹ mimọ́ ki a si fi ẹjẹ ya a si mimọ́ ki o to le wọ Ibi Mimọ́; ni Ọjọ Etutu oun a si maa wọ awọn àṣàyàn aṣọ ọgbọ ki o ba le ni idaniloju pe wọn jẹ alaileeri, ki o to wọ Ibi Mimọ́ Julọ.

Ko si nnkan kan ninu iyara naa yatọ si Apoti Majẹmu, ninu eyi ti awọn walaa okuta Ofin Mẹwaa, ti i ṣe ifẹ Ọlọrun ti o ṣe e foju ri wà. Apoti Majẹmu naa jẹ apoti ti a fi wura pipe tẹ́ lode ati ninu. Ideri rẹ jẹ kiki wura, a si pe e ni Itẹ-Aanu. Awọn kerubu ti a fi kiki wura ṣe ni wọn gbé si igun mejeeji itẹ-aanu naa, wọn si kọju si ara wọn, wọn n wo itẹ-aanu naa. Nihin ninu awọsanma ni Ifarahan Mimọ́ Ọlọrun wà, laaarin awọn kerubu (Orin Dafidi 80:1; 99:1).

Ko si iná ni Ibi Mimọ́ Julọ. Ṣugbọn wọn ha tun fẹ imọlẹ miiran nigba ti Ọlọrun ba wà nibẹ? Ninu Ifihan a kà nipa Jerusalẹmu Titun: "Ilu na kò si ni iwá õrùn, tabi oṣupa, lati mã tan imọlẹ si i: nitoripe ogo Ọlọrun li o ntàn imọlẹ si i, Ọdọ-Agutan si ni fitila rẹ̀" (Ifihan 21:23).

### Ọjọ Etutu

Ni Ọjọ Etutu ti olori alufaa i maa wọ Ibi Mimọ́ Julọ ni o ni lati mú ẹjẹ pẹlu rẹ lati ara ẹbọ ẹṣẹ, (diẹ ninu eyi ti a ti fi sori pẹpẹ wura) ati iná mimọ́ ati turari lati ibi pẹpẹ wura). O ni lati bẹrẹ mọ́lẹ̀ lati gba abẹ aṣọ ikele naa kọja bi o ti n fi tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀ ati tẹ̀rùtẹ̀rù bọ́ si iwaju Ọlọrun. Eefin turari, ti n goke bi adura ati iyin aidẹkun, jẹ aabo laaarin oun ati ifarahan Ọlọrun ti o ni ẹ̀rù. "Ki o si fi turari na sinu iná niwaju OLUWA, ki ẽfin turari ki o le bò itẹ́-ãnu ti mbẹ lori ẹri, ki on ki o má ba kú" (Lefitiku 16:13).

A ti ri i pe a ni lati jẹ́ mimọ́, ẹni ti a yà sọtọ, pẹlu Ẹjẹ naa ninu ọkàn wa, ki a to le wọ Ibi Mimọ́ Julọ. Adura wa n goke lọ leralera pẹlu iyin ati ifararubọ bi turari ti n jò lori pẹpẹ. A ko dẹkun lati maa bẹbẹ fun Ẹjẹ nì lati bori aye wa ki a ba le maa jẹ́ mimọ́. Ṣugbọn nnkan ṣi wa fun wa lati gbà.

### Agbára ni Ikẹyin Ọjọ

Olori alufaa a maa wọ Ibi Mimọ́ Julọ lẹẹkan lọdun, ṣugbọn o ni lati jade nigba gbogbo nitori "a kò ti iṣi ọ̀na ibi mimọ silẹ niwọn igbati agọ́ ekini ba duro" (Heberu 9:8). Ẹmi Mimọ ti bà le awọn eniyan mimọ labẹ Ofin, lati fi ororo yàn wọ́n fun iṣẹ pataki. Ṣugbọn ifororoyan naa kan wà fun saa kan ni. Itujade Ẹmi Mimọ́ fun gbogbo-gbo eyi ti yoo fun ni ni agbara fun sisin ni a fi pamọ de igba ikẹyin, eyi ti Joẹli sọ nipa rẹ̀: "Yio si ṣe, nikẹhìn emi o tú ẹmi mi jade si ara enia gbogbo" (Joẹli 2:28). Peteru fi idi eyi mulẹ ni Ọjọ Pẹntekọsti nigba ti o kede si awọn eniyan pe, "Eyi li ọ̀rọ ti a ti sọ lati ẹnu woli Joẹli wá" (Iṣe Awọn Apọsteli 2:16). Ẹmi ti bà le gbogbo awọn ti o wa ni iyara oke ti wọn pejọ pọ ni ọkàn kan lati duro de Olutunu ti a ti ṣeleri, wọn si fi ède titun sọrọ gẹgẹ bi ẹ̀ri pe Ẹmi Mimọ ti bà le wọn. Eyi mu ki ẹru ba awọn ti o gbọ́ wọn, ṣugbọn Peteru fi ọkàn wọn balẹ pe imuṣẹ asọtẹlẹ ni o jẹ́, agbara fun sisin lori ọkunrin ati obinrin, arugbo ati ọdọmọde, Ju ati Heleni, "ẹnikẹni ti o ba pe orukọ Oluwa."

### Aṣọ Ikele Ya

Nnkan kan ṣẹlẹ laaarin akoko ti olori alufaa i maa wọ Ibi Mimọ Julọ lẹẹkan ṣoṣo lọdun, ati Ọjọ Pẹntekọsti nigba ti Ẹmi Mimọ ba le awọn eniyan ninu iyara oke. Lẹyin ti awọn Ọmọ Israẹli de Ilẹ-Ileri wọn kọ́ Tẹmpili kan gẹgẹ bi apẹẹrẹ Agọ (ni aginju), eyi ti o ni Ibi Mimọ ati Ibi Mimọ Julọ. Ninu rẹ̀ ni Apoti Majẹmu Ọlọrun joko lẹyin aṣọ ikele pẹlu gbogbo ọ̀wọ̀ ti o ti ní ninu Agọ. Iṣẹ-Isin kan naa ni awọn alufaa n ṣe bi ninu aginju.

Lẹyin naa Jesu de lati mu Ofin ṣẹ. Irubọ ọdọ-agutan ko ṣanfaani mọ, nitori Jesu ni Ọdọ-Agutan Ọlọrun; ewurẹ idasilẹlọ ko ṣanfaani ni Ọjọ Etutu, nitori Jesu di ewurẹ idasilẹlọ fun wa. Jesu jiya lẹyin ibudo lati sọ awọn eniyan Rẹ̀ di mimọ́ pẹlu Ẹjẹ Rẹ̀, nitori naa a ko fẹ ẹbọ ẹṣẹ mọ́. Loju kan naa ti O si kú lori agbelebu, aṣọ ikele wiwuwo nì ti a fi aṣọ pupa ati aṣọ aró ati aṣọ ẹlese-aluko ati wura hun faya lati oke délẹ̀, o si ṣi ọna silẹ sinu iyara ti inu, ti o lọ́wọ̀, nibi ti Ifarahan Ọlọrun wà. Paulu sọ fun wa pe aṣọ ikele naa duro fun ara Jesu, nigba ti a si fa ara Rẹ̀ ya fun wa, a le wọle sinu ọna titun ati aayè, ohun ti o logo ju eyi ti ẹnikẹni ninu awọn eniyan mimọ́ igbà Majẹmu Laelae jẹ anfaani rẹ̀ lọ.

**Igbà ti o Dara Jù**

Olori alufaa a maa mu ẹjẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ lọwọ a si maa wọ inu Ibi Mimọ́ Julọ tẹ̀rutẹ̀ru; ṣugbọn nisisiyii awa le mu Ẹjẹ Jesu ti o ti gba wa là ti o si ti sọ wa di mimọ́, ki a si wọ inu Ibi Mimọ́ Julọ pẹlu igboya (Heberu 10:19, 20). Jake jado iwe Heberu, Paulu sọ fun wa pe igba Majẹmu Titun sàn ju ti Laelae lọ. Agọ nì jẹ aworan eto Ọlọrun fun irapada, Jesu si wá lati mu un ṣẹ. Lonii a ni eto alufaa ti o san ju bẹẹ lọ (Heberu 7:20-28), Majẹmu ti o dara jù (Heberu 8:6), ati ẹbọ ti o san ju ti ẹranko lọ (Heberu 9:23).

**Si Gbogbo Eniyan**

Awọn Ọmọ Israẹli jẹ́ ayanfẹ Ọlọrun, a si fi ijinlẹ Ọrọ Ọlọrun le wọn lọwọ. Nipasẹ wọn ni a ti fi Ọrọ Rẹ̀ fun araye. Ṣugbọn nigba ti Jesu nipa iku Rẹ̀ ṣí ọna silẹ si Ibi Mimọ́ Julọ, gbogbo eniyan ni o ni ominira lati de ẹ̀kun rẹ́rẹ́ igbala. (Ẹkun rẹrẹ igbala ni ifiwọni Ẹmi Mimọ́, pẹlu idalare ati isọdimimọ). "Enia gbogbo", ti Joẹli ati Peteru sọ nipa rẹ̀, ni wọn ní anfaani nisisiyii lati wá gbadun irẹpọ mimọ́ pẹlu Ọlọrun, ki wọn si ni ifarahan Rẹ̀ lati maa wà ninu igbesi-ayé wọn lojoojumọ.

Nigba ti Jesu n dagbere fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, O ṣeleri Olutunu fun wọn, ani Ẹmi Mimọ́. Oluwa wi pe Ẹmi yii n **bá** wọn gbé nigba naa, ṣugbọn lẹyin igba ti Oun ba ti lọ Ẹmi naa yo bà le wọn yoo si **wà** ninu wọn (Johannu 14:17). A mọ̀ pe a kò ti i fi Agbara Ẹmi Mimọ wọ awọn ọmọ-ẹyin ki Jesu to ku, nitori O wi pe, "Anfani ni yio jẹ fun nyin bi emi ba lọ: nitori bi emi kò ba lọ, Olutunu kì yio tọ̀ nyin wá: ṣugbọn bi mo ba lọ, emi o rán a si nyin" (Johannu 16:7). Ni ti Olutunu naa O si wi pe: "Nigbati on, ani Ẹmí otitọ ni ba de, yio tọ́ nyin si ọ̀na otitọ gbogbo" (Johannu 16:13). Ki olukuluku ọkàn ti a ti sọdimimọ ki o gbadura tọkantọkan lati ri ifarahan Ẹmi Mimọ́ ti n bá ni gbé naa, eyi ti yoo ṣe e ni imọlẹ ninu ayé yii ti yoo si fun un ni agbara fun iṣẹ-isin aṣeyọri.

**AWỌN IBEERE**

1 Nibo ni Ibi Mimọ́ Julọ?
2 Bawo ni eniyan ṣe le wọ ọ? (Ta ni, nigba wo ati lori ẹ̀tọ́ wo)?
3 Ki ni ṣẹlẹ si aṣọ-ikele nigba ti Jesu kú? Bawo ni eleyi ṣe kàn wa?
4 Nigba wo ni itujade ifiwọni Ẹmi Mimọ́ bẹrẹ?
5 Ki ni ṣe ti a kò le ṣai ni ifiwọni Ẹmi Mimọ́? Ta ni le ri i gbà?